# ERO ONIGBAGBỌ́

**Filippi 4:8**

**ẸKỌ 341 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: “Ka iṣẹ rẹ le OLUWA lọwọ, a o si fi idi iro-inu rẹ kalẹ” (Owe 16:3).**

**Episteli**

Paulu ti bẹ ilu ti a n pe ni Filippi ni Makedonia wò ninu irin-ajo rẹ ikeji ati ikẹta fun itankalẹ Ihinrere. Ninu adura rẹ, o dupẹ lọwọ Ọlọrun fun iranti ti o mayọ̀ kún ọkàn rẹ nipa awọn ọmọ-ẹyin ti o wà nibẹ̀, ati fun idapọ̀ mimọ́ wọn (Filippi 1:3-5). Awọn ọmọ-ẹyin ti o wa ni Filippi pẹlu ṣe iranti Paulu. Wọn fi ọrẹ ranṣẹ si i lati fi ṣe iranlọwọ fun un ninu iṣẹ itankalẹ Ihinrere ti o n ṣe. Ni akoko kan wọn fi ọrẹ wọn rán ẹni kan ti a n pe ni Epafroditu. Nigba ti Paulu kọ iwe idúpẹ́ si awọn ara Filippi o wi bayii pe: “Mo si kún nigbati mo ti gbà nkan wọnni ti a ti rán lati ọdọ nyin wá lọwọ Epafroditu, ọrẹ olõrùn didùn, ẹbọ itẹwọgbà, ti iṣe inu didùn gidigidi si Ọlọrun” (Filippi 4:18).

Iwe ti a n pe ni Filippi ni Episteli Paulu si ijọ ti o wà ni Filippi. Ọlọrun mi si Paulu lati kọ ọ́, awọn ọmọ-ẹ̀yin Jesu si ti ri itọni ati iwuri gbà ninu rẹ̀ lati igba nì titi di oni-oloni.

**Èrò**

Iwe Paulu sọ nipa igbesi-ayé Onigbagbọ́ ati nipa diẹ ninu ojuṣe rẹ̀. Paulu ṣe akọsilẹ ohun wọnni ti o dara ti o si ṣanfaani fun awọn ti a gbàlà lati maa ṣe aṣaro nipa rẹ̀. Erò Onigbagbọ́ yatọ si eyi ti o ti wà lọ́kàn rẹ̀ ki a to gbà ọkàn rẹ̀ là. Bi Isaiah ti n pé awọn eniyan si ironupiwadà, o wi pe: “Jẹ ki enia buburu kọ̀ ọ̀na rẹ̀ silẹ, ki ẹ̀lẹṣẹ si kọ̀ ironu rẹ̀ silẹ; si jẹ ki o yipada si OLUWA, on o si ṣanu fun u, ati si Ọlọrun wa, yio si fi ji lọpọlọpọ” (Isaiah 55:7). Ọlọrun sọ ní ti awọn eniyan Rẹ̀ pe: “Emi ó fi ofin mi si inu wọn, emi o si kọ wọn si ọkàn wọn” (Heberu 8:10).

Erò rere nikan kò le sọ eniyan di Onigbagbọ́, ṣugbọn èrò buburu le sún eniyan dẹ̀ṣẹ. Lẹyin ti eniyan ba ti ri aanu ati idariji ẹ̀ṣẹ rẹ̀ gbà, yoo fẹ ki alaafia yii ki o wà ninu ọkàn oun titi. Wolii Isaiah wi pe: “Iwọ o pa a mọ́ li alafia pipé, ọkàn ẹniti o simi le ọ, nitoriti o gbẹkẹle ọ” (Isaiah 26:3).

Dafidi pẹlu, mọ̀ bi o ti ṣe ohun pataki tó fun Onigbagbọ́ lati ṣọ́ èrò ọkàn rẹ̀. O gbadura pe ki aṣaro tabi èrò ọkàn rẹ̀ ati ọ̀rọ oun pẹlu le jẹ itẹwọgbà fun Ọlọrun (Orin Dafidi 19:14). Dafidi bẹ Ọlọrun pe ki o yẹ ọkàn oun wò lati mọ̀ bi ọ̀na buburu kan ba wà ninu oun (Orin Dafidi 139:23, 24).

Ọlọrun mọ èrò wa, O si ni akọsilẹ kan fun awọn ti o n ṣe aṣaro nipa Rẹ̀. Wolii Malaki wi pe: “Awọn ti o bẹ̀ru OLUWA mba ara wọn sọ̀rọ nigbakugba; OLUWA si tẹti si i, o si gbọ́, a si kọ iwe-iranti kan niwaju rẹ̀, fun awọn ti o bẹ̀ru OLUWA, ti wọn si nṣe aṣaro orukọ rẹ̀” (Malaki 3:16).

**Ohun ti i ṣe Otitọ**

Gẹgẹ bi a ti ri i pe èrò wa ṣe ohun pataki, ki ni ohun ti o yẹ ki a maa ṣe aṣaro le lori? Paulu wi pe, “Ohunkohun ti iṣe õtọ … ẹ mã gba nkan wọnyi rò.” Ohun pupọ lode oni ni o jẹ èké. Bawo ni a ṣe le mọ eyi ti i ṣe otitọ? Nigba kan nigba ti Jesu n gbadura ti O si n ba Ọlọrun sọrọ, O wi pe, “Otitọ li ọ̀rọ rẹ” (Johannu 17:17). Ọrọ Ọlọrun ni Bibeli, otitọ si ni Bibeli. O n kọ ni pe awọn ileri Ọlọrun jẹ́ otitọ. A ka a pe “idajọ OLUWA li otitọ, ododo ni gbogbo wọn” (Orin Dafidi 19:9). Awọn ileri Ọlọrun, nipa ibukun ati idajọ kun fun aṣaro rere lọpọlọpọ. Ṣiṣe aṣaro lori awọn nnkan wọnyi ti o jẹ otitọ, yoo mu ki eniyan pinnu lọkan ara rẹ̀ lati fi ayé rẹ̀ fun Oluwa. Nigba naa yoo ni anfaani lati pe gbogbo awọn ibukun iyanu wọnni ti a ti ṣeleri ni ti rẹ̀.

**Eke**

Satani ni baba èké, kò si si otitọ ninu rẹ̀ (Johannu 8:44). Oun ni ọta ti ẹmi wa, oun yoo maa wá ọ̀na lati mu wa gba èké gbọ́ ati lati maa ṣe aṣaro nipa ohun ti ki i ṣe otitọ. Nigba ti iwọ ba n ṣaisan, o le maa mu ki o ni ero wi pe, Ọlọrun ki yoo wò ọ san; ṣugbọn Oluwa wi pe, “Emi li OLUWA ti o mu ọ lara dá” (Ẹksodu 15:26).

Ẹ jẹ ki a wo apẹẹrẹ ẹni kan ti o n ṣe aṣaro nipa ohun ti ki i ṣe otitọ. Satani kó sinu ejò, o si tan Efa jẹ ninu ọgba Edẹni. O wi fun un pe, "Ẹnyin ki yoo kú ikú kikú kan" (Gẹnẹsisi 3:4). Ọlọrun ti wi pe: "Ninu igi imọ̀ rere ati buburu nì, iwọ kò gbọdọ jẹ ninu rẹ̀: nitoripe li ọjọ́ ti iwọ ba jẹ ninu rẹ̀ kikú ni iwọ o kú" (Gẹnẹsisi 2:17). Nitori ti Efa gba ẹ̀tan ti Satani gbé le e lọwọ rò, a dá an wò, o si dẹ̀ṣẹ. A yà a nipa kuro lọdọ Ọlọrun, bẹẹ ni o kú ikú ẹmi. Ki i ṣe bẹẹ nikan, ṣugbọn ẹ̀ṣẹ ti mú ki gbogbo eniyan di okú nipa ti ẹmi. Ọna kan ṣoṣo ti ẹnikẹni le fi di alaaye ni pe ki a gba ọkàn rẹ̀ là nipa Ẹjẹ Jesu.

Ẹ jẹ ki a maa ṣe aṣaro nipa ohun ti i ṣe otitọ. A sọ nipa Jesu pe, Oun ni "àjara tootọ" (Johannu 15:1), "onjẹ otitọ" (Johannu 6:32), ati "Imọlẹ otitọ́" (Johannu 1:9).

**Òtítọ́**

Otitọ jẹ ohun miiran ti o ni lati wà ninu èrò wa. Lati jẹ́ oloootọ ni pe ki a jẹ ẹni ti o n huwa ti kò ni èrú ati ẹni ti o ṣe e fọkàn tan. A le fi ọkàn tan ẹni ti o n ṣe olotitọ lati huwa ẹtọ. Awọn eniyan ki i fi ọkàn tán alaiṣootọ. Siwaju sii awọn eniyan ki i fẹran awọn to n ṣèrú ti wọn kò si ṣe fọkàn tán. O ṣe pataki fun wa lati jẹ́ oloootọ, ki a si maa ṣe aṣaro nipa iwa otitọ. O ṣe e ṣe nigba kan, ki ẹni kan maa ji iṣẹ ẹnikeji rẹ̀ kọ silẹ ni ile-iwe. Satani yoo fẹ lati mu ki awọn ọmọde miiran maa ronu nipa iwa aiṣootọ yii. Oun yoo sọ fun wọn pe o rọrùn yoo si gbà wọn niyanju lati ṣe bẹẹ pẹlu. Nigba ti wọn ba rò ó, ti wọn si pinnu rẹ̀ tán, ohun ti yoo tẹle e ni pe wọn o ṣe e. Abajọ ti Paulu fi gbà wa niyanju lati maa ronu nipa ohun ti i ṣe otitọ.

**Ẹ̀tàn**

Ninu Bibeli, a ri apẹẹrẹ awọn ti o ronu nipa ohun ti ki i ṣe otitọ. Awọn kan ninu awọn ọmọ-ẹ̀yin n ta ohun ini wọn, wọn si n kó owó naa fun awọn Apọsteli. Anania ati iyawo rẹ̀, Safira, rò nipa ọ̀na kan ti awọn le gbà fi ara han bi ẹni ti o n ṣe ohun kan naa. Wọn ta ohun ini wọn. Wọn gbèro wọn si fi imọ ṣọkan nipa ohun ti wọn o ṣe. Anania mu apa kan ninu owo naa tọ awọn Apọsteli wá. O si ṣe bi ẹni pe gbogbo owo naa ni. O huwa ẹ̀tan ati aiṣootọ. Ikú ni ijiyà Anania ati Safira. Eké jẹ ohun ti kò dara, i baa ṣe pe a sọ ọ lẹnu tabi a hú u niwà. A ni lati jẹ́ olotitọ, ki a si maa ronu nipa ohun ti i ṣe otitọ.

**Titọ́ ati Mimọ́**

Lati jẹ́ olotitọ, gẹge bi ofin Ọlọrun, ni lati jẹ́ olododo ati ẹni diduro-ṣinṣin, ki igbesi-ayé wa si ṣe deedee pẹlu ilana ti a fi lelẹ ninu Iwe Mimọ. Lati jẹ́ ẹni mimọ́ ni lati wà lai ni ẹ̀bi, alailẹ̀ṣẹ, ati alaileeri. Ronu nipa nnkan wọnyi. Iru iwe oriṣiriṣi ti eniyan n kà, aworan ati iran ti o n wò, ati iru orin ati itàn ti o n gbọ́, a maa lagbara lori èro ọkàn rẹ̀. Agbára yii kò pin sori èro wa nikan, ṣugbọn o kan iwa wa ati iṣe wa pẹlu. Ọpọlọpọ awọn ọmọde ati ọ̀dọ́ paapaa ni o hàn gbangba pé wọn ti huwa buburu ati iwa-ọdaran kan naa ti wọn ti ri ninu aworan sinima, tẹlifiṣọn, ati eyi ti wọn ti gbọ́ lori ẹrọ redio. Wọn rò nipa wọn, wọn ṣe àṣàrò lori wọn, wọn si dán wọn wò. Fun awọn miiran, irú nnkan bayii ti ṣe okunfa ikú wọn, tabi ikú fun awọn ẹlomiran ati ijiya fun awọn paapaa.

Má ṣe rò pe eniyan le maa fi oju-kọrọ wo ẹ̀ṣẹ ki ẹni naa si rò pe ohun ti oun ti ri kò ni i ṣe ohunkohun lọkàn oun. Eyi a maa fun Satani ni anfaani pupọ si i lati mu awọn ero aimọ́ ati aitọ wá sinu ọkàn eniyan ati lati dán oluwa rẹ̀ wò lati ṣe ibi. Ki ni ṣe ti eniyan ni lati fi ohun buburu ba ara rẹ̀ jẹ nigba ti ohun ti o mọ́ ti o si wu ni wà fun igbadun wa? Ki ni ṣe ti iwọ kò fi maa ka iwe ti o dara? Ki ni ṣe ti iwọ kò fi maa tẹti-lelẹ lati maa gbọ́ orin ti o dara? Ki ni ṣe ti iwọ kò le maa wo ohun wọnni ti Ọlọrun dá? Awọn wọnyi ki i dán ni wò lati dẹ̀ṣẹ. Awọn ohun ti ẹ̀dá ọwọ Ọlọrun – itanna inu ọgbà, oorùn ti nwọ̀ ti o si rẹ̀ dodo, odo ti n ṣàn lẹgbẹ oke – gbogbo wọn ni o n yin Ọlọrun ni ọ̀na ti wọn, wọn si n rán wa leti pe ki awa ki o ṣe bẹẹ gẹgẹ.

**Awọn Ohun ti i ṣe Fifẹ**

Ronu nipa awọn ohun ti i ṣe fifẹ! Ki ni i ṣe fifẹ? Awọn ohun ti o maa n rú ọkàn wa soke lati fẹran ati lati sọ̀rọ rere. Orin nipa aanu Ọlọrun, ọ̀rọ arofọ nipa ikẹ́ Rẹ̀, aworan nipa igbesi-ayé Jesu -- awọn wọnyii kò ha n rú ọkàn wa soke lati fẹran Rẹ̀ si i? Wo bi Jesu Kristi ti fẹran wa, to bẹẹ ti O fi ẹmi Rẹ̀ lelẹ̀ ki awa ba le ri igbala. Njẹ eyi kò ha mu ki o fẹran Rẹ̀? A fẹran Rẹ̀ nitori Oun ni o kọ́ fẹ wa.

Njẹ iwọ ha n rò nipa iwa rere ti o wà ninu awọn ẹlẹgbẹ rẹ ni ile-ẹkọ, awọn ọrẹ rẹ, ati awọn eniyan Ọlọrun? Satani ni olufisun awọn ará. O fẹ ki a maa rò nipa aṣiṣe ti ẹni kan ṣe, tabi ọ̀rọ ailọgbọn ti ẹni kan

sọ, tabi iwà ailọgbọ́n ti ẹni kan hù, tabi ohun ti o fara jọ ibi. Bi a ba gba iru èro bẹẹ láyè ninu ọkàn wa, wọn a maa mu ki a ni èrò ti kò tọ́ si ẹlomiran. "Bi ìwa-titọ́ kan ba wà, bi iyin kan ba si wà, ẹ mã gbà nkan wọnyi rò." Diẹ ni awọn eniyan ti o wà ni ayé ti a kò le ri ohun kan ninu wọn eyi ti o dara ti a le fi yin wọn. Eniyan ni lati maa rò nipa iwà rere ati iwà ti o ni iyin ti o wà lara awọn Onigbagbọ́ ẹlẹgbẹ rẹ̀, ki o si gbadura tọkàntọkàn pe ki Ọlọrun ran olukuluku wọn lọwọ lati jẹ́ Onigbagbọ́ tootọ, ẹni ti a fi idi rẹ̀ mulẹ ninu "ọrọ rere ati iṣẹ rere gbogbo." Ẹ jẹ ki a maa rò nipa ohun wọnni ti yoo rú ifẹ wa soke si Ọlọrun ati awọn eniyan Rẹ̀.

**Ti o ni Ihin Rere**

Awọn Onigbagbọ́ a maa rò nipa ohun wọnni ti o ni ihin rere, dipo ki wọn maa rò nipa ohun wọnni ti o le mú wọn rẹ̀wẹ̀si, ti o si le mu iyemeji kún inu wọn. Onigbagbọ́ kò gbọdọ feti si òfófó, ki a ma ṣẹṣẹ wá sọ wi pe ki o tilẹ rò ó wò. Bibeli fun wa ni apẹẹrẹ awọn kan ti wọn gba ihin buburu rò. A rán awọn amí mejila lati lọ wò Ilẹ Kenaani. Nigba ti wọn pada bọ̀ awọn amí mẹwaa fi iroyin buburu fun awọn eniyan, wọn sọ nipa awọn ilu-olodi ati awọn òmiran. Ọ̀kan ninu awọn amí ti o mu ihin rere wá wi pe, "Ẹ jẹ ki a gòke lọ lẽkan ki a si gbà a; nitoripe awa le ṣẹ́ ẹ" (Numeri 13:30). Awọn eniyan naa kò rò nipa ileri Ọlọrun. Wọn gba ihin buburu rò, wọn gbá a gbọ́, wọn si n rin kiri ninu aginju fun ogoji ọdún.

"Bi ìwa titọ́ kan ba wà, bi iyin kan ba si wà, ẹ mã gba nkan wọnyi rò." Awọn ọ̀rọ wọnyii kó gbogbo imọran miiran nipa èrò wa pọ̀. A lé mọ̀ èro rere tabi buburu lọna bayii: iwa titọ́, iwa rere, tabi iwa ọmọ-luwabi ha wà ninu rẹ̀ bi? Iyin ha wà ninu rẹ̀, o ha ṣe e fara mọ́, o ha ni ọlá bi?

**Wiwọ inu Ọkàn**

Eniyan le ṣalai-lagbara lati paṣẹ fun èro pe ki o má ṣe wọ inu ọkàn oun, ṣugbọn oun le kọ̀ lati gbà a làye lati duro nibẹ. Le èrò buburu wọnni jade ti Satani n fẹ lati fi sibẹ, ki wọn má ba wọ inu ọkàn rẹ lọ, wọn a si di ẹ̀ṣẹ. A fi imọran yii ṣe apẹẹrẹ fun wa: Eniyan kò le sọ pe ki ẹyẹ má ṣe fo kọja lori oun, ṣugbọn o le kọ̀ fun ẹyẹ lati kọle si oun lori. Ẹ̀wẹ̀ o le ṣoro fun eniyan lati dá èro buburu duro pe ki o ma ṣe wọ inu ọkàn oun, ṣugbọn o le kọ̀ lati gba wọn làye nipa ṣiṣe aṣaro lori Ọrọ Ọlọrun ati Ọlọrun. Nipa sisọ ọ̀rọ inu Bibeli, Jesu mu ki eṣu fi Oun silẹ. A le mu awọn akọsori ti a ti kọ́ wá si iranti wa tabi awọn ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun ti a n kà ninu Bibeli kika wa ojoojumọ; bi a si ti n fi iwọnyi kún inu ọkàn wa, eṣu yoo fi wa silẹ pẹlu.

Paulu wi pe: "Ẹ maa yọ̀ ninu Oluwa nigbagbogbo: … Ẹ máṣe aniyàn ohunkohun; ṣugbọn ninu ohun gbogbo, nipa adura ati ẹbẹ pẹlu idupẹ́, ẹ mã fi ibere nyin hàn fun Ọlọrun. Ati alafia Ọlọrun, ti o ju ìmọran gbogbo lọ, yio ṣọ ọkàn ati ero nyin ninu Kristi Jesu" (Filippi 4:4-7).

## AWỌN IBEERE

1. Ta ni kọ iwe yìí si awọn ara Filippi?
2. Nigba wo ni o bẹ Filippi wò?
3. Ki ni ohun ti a ranti nipa Lidia ati nipa onitubu ilu Filippi?
4. Ọna wo ni awọn ará Filippi gbà fi ranti Paulu?
5. Bawo ni Paulu tin ṣe iranti wọn?
6. Ki ni ohun ti èrò maa n ṣe ninu ọkàn?
7. Bawo ni èro wa ṣe le lagbara lori iwà wa?
8. Bawo ni a ṣe le mọ̀ èro rere ati buburu?
9. Darukọ awọn ẹ̀dá ọwọ́ Ọlọrun ti wọn n yin Ọlọrun, ti o si n fi hàn fun wa pe o yẹ fun wa lati maa ṣe bẹẹ pẹlu.
10. Darukọ awọn nnkan miiran ti o lagbara lori èrò wa.